
# Ẹ̀rọ Ayára bíi àṣá
# (Kọ́ńpútà)



## Ẹ̀kọ́ àwọn ẹ̀yà ayára bíi àṣá

# Àyára bíi àṣá

## I Ìfihàn




Bákan náà ni gbogbo àwọn ẹ̀rọ dígítà ( Àyára bíi àṣá , fóònù àyárà, tí a ń lò lónìí ṣe ṣiṣẹ́.

## II Àwọn ẹ̀yà ẹ̀rọ àyára bíi àṣá

### 1) Ìbòjú

Ẹ̀rọ ìbòjú jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀rọ agbègbè ti ìjáde, a ń pè ni ẹ̀rọ agbègbè ìjáde nítorí pé àwọn iró ti a bá tẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀rọ ìtẹ̀wé, orí ni tí ń jáde. Àwọn ẹ̀rọ ìbòjú pé oríṣi, ìbòjú ( ”14, ”17, “24 … ). Orúkọ àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọn jáde ni ( Samsung, Sony, Sharp, Nec, HP… ).

Àkiyèsí: “14 jẹ́ àtaǹpàkò mẹ́rìnlà

2) Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé

Ẹ̀rọ ìtèwé jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀rọ ìwọlé, nitórí wí pé àwọn iró tí a bá tẹ̀ wọlé máa gbà agbédéméjì fi jáde sí orí ìbòjú.
Àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé ti a ń lò fi kọ èdè Faransé, orúko wọn ni AZERTY , àwọn èyí ti a ń lò fi kọ èdè gẹ́ẹ̀sì orúkọ wọn ni QWERTY, fi kọ èdè Yorùbá tàbí àwọn èdè ìlú adúláwọ̀ ẹ̀rọ ìtẹ̀wé EITWA ti ilé iṣẹ́ EITWA ni a ń lò.
Pẹ̀lú ẹ̀rọ ìtẹ̀wé EITWA a tún lè kọ Faransé, Gẹ́ẹ̀sì, àti gbogbo èdè ìlú adúláwọ̀ bíi 2000.

3) Agbédéméjì ìṣe


Ẹ̀yà pàtàkì kan ni ẹ̀ya agbédéméjì ìṣe, inú ẹ̀yà yìí ni àwọn ẹ̀yà mí ìn ti wọn tún ṣe pàtàkì fún ìṣiṣẹ́ kọ̀ńpútà wà. Àwọn èyà wọ̀nyìí ni :

### 3,1) amúnáwá ( Generator )



Ẹ̀yà òpèsè iná mànàmáná  yìí ni máa mú iná wá fún ẹ̀rọ àyára bíì àṣá, ti kò bá ṣiṣẹ́, ti ó bá dáṣẹ́ dúro iná kò ní wá inú kọ̀ńpútà mọ́, òhun náà á dáṣẹ́ dúro. Inú agbédéméjì ìṣe ni ó wà, àmọ́ wọ́n máa tà á lọ́tọ̀ọ́ . Amúnáwá yìí  ni máa dí agbára òpèsè iná gbogbogbò kù, agbára yìí má kúrò ni folti 220 fi dé folti 5 tàbí folti 12.

### 3.3  Ẹ̀rọ ìṣe  ( procesor )





Ẹ̀rọ ìṣẹ ni nǹkan pàtàkì fún kọ̀ńpútà inú agbedeméjì ló wà. Ti a bá fẹ́ fi ẹ̀rọ ayára bíì àṣá wé èèyàn a yóò sọ pé , nǹkan ti ọkàn jẹ́ fún èèyàn ni ẹ̀rọ ìṣe jẹ́ fún ẹ̀rọ kọ̀ńpútà. Nǹkan tó fi hàn pé ẹ̀yà pàtàkì ni ẹ̀rọ ìṣe.Ti ẹ̀rọ yìí bá dáṣẹ́ dúro, kọ̀ńpútà pàápàá kò ni ṣiṣẹ́ mọ́.
Inú ẹ́rọ ìṣe yìí ni àwọn ẹ̀ya mí ìn wà :
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  àfikún  +
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  ìyọ̀kù    –
- ẹ̀yà ẹ̀rọ  ìlọpo     *
- ẹ́ya ẹ̀rọ ìdá        /

Àti  àwọn ẹ̀yà ẹ̀rọ mí ìn.
Gbogbo àwon ẹ̀yà wọ̀nyìí ni kọ̀ńpútà  máa lò fi ṣe gbogbo àwọn ìṣirò ẹ, pẹ̀lú àwọn  iṣẹ́ mí ìn.
Àwọn ilé iṣẹ́ ti rọ àwọn ẹ̀rọ ìṣe wọ̀nyìí ni INTEL, IBM, AMD, CENTAUR, TEXAS…
INTEL ló ṣíwájú  gbogbo àwọn ilé iṣẹ́ náà ni gbogbo àgbáyé. Ọ̀pọ̀lọ̀pọ̀ àwon kọ̀ńpútà tábìlì àti àwọn kọ̀ńpútà alágbéka ni wọ́n ń lò ẹ̀rọ ìṣe INTEL, àwọn ìwọ̀n kan ni wọ́n ń lò AMD àti àwọn èyì tó kù.

### 3.2 aago


Aago yìí ni ẹ̀rọ ìṣe ( procesor )  máa lò fún ètò iṣẹ́ rẹ̀, bí tí aago yìí  bá ṣe yara ṣiṣẹ́, bẹ́ẹ̀ ni ẹ̀rọ ayára bíì àṣá náà máa yara. Àwọn ẹ̀rọ tí wọ́n ń tà lónìí:   àgbóhunsáfẹ́fẹ́ wọn ni Ghz 4 dé 8.
àmọ́ agbóhunsáfẹ́fẹ́  yìí  máa lọ sókè  lóṣù mẹ́fà mẹ́fà.

**3.4 Ẹ̀rọ ìrantí ( RAM )**




Inú ẹ̀rọ ìrantí tí orúkọ ẹ jẹ́ RAM ( Random Access Memory ) ni a máa kó àwọn "data" ti a bá fẹ́ lò lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ pamọ́ sí, a lè kọ "data" sínú ẹ̀rọ yìí, a sì tún lè kà èyí ti wọ́n tí kọ sínú ẹ. Nitórí ẹ ni wọ́n fi fún ni orúkọ RAM (Random Access Memory) ìtúmo ẹ ni ẹ̀rọ ìrantí ti a lè kọ, ti a sì tún lè kà.
Bíi àpẹẹrẹ tí ẹ̀rọ ìṣe bá fẹ́ ṣẹ ìṣirò yìí 2+3, tó bá fẹ́ fi méjì fi kún mẹ́tà tí yóò jẹ́ marún ùn , yóò kà 2 sínú ẹ̀rọ ìrantí yìí tí yóò sì gbé pamọ́, lẹ́yìn ẹ yóò ka 3 sínú ẹ tí yóò sì gbé e pamọ́ bákan náà, lẹ́yìn ẹ yóò wa fi méjì fi kún mẹ́tà ti ń jẹ́ marún ùn, yóò wà kọ ọ́ sínú ẹ̀rọ ìrántí yìí. Ẹ̀rọ ìṣirò lè fi marún ùn yìí hàn lórí ẹ̀rọ ìbòjú. Go 4 dé 8 ni agbára ẹ̀rọ ìrántí ti àwọn kọ̀ńpútà lò ni òde onìí.
Ẹ̀rọ ìrantí yìí dàbí tábìlì fún ẹ̀rọ ìṣe ( procesor ) ti kọ̀ńpútà , inú ẹ ni máa kó àwọn "data" tó bá fẹ́ lò fi ṣiṣẹ́ lẹ́sẹ̀kẹ́sẹ̀ sí.
Tí ẹ bá ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú kọ̀ńpútà ẹ máa rántí láti máa dà "data" tó wà nínú ẹ̀rọ ìrantí sínú àwo líle. Bí kò ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ yóò pàdànù gbogbo iṣẹ́ ti ẹ ṣe sẹ́yin wa lọ.

**3.5 Ẹ̀rọ Ìrantí ( ROM )**




Ìtúmọ́ ẹ̀rọ ìrantí ROM ( Read Only Memory ) ni ẹ̀rọ ti a lè kà àmọ́ ti a kò lè kọ. Ilé-iṣẹ́ tí rọ kọ̀ńpútà ni máa kọ ètò yẹn sórí ẹ. Ètò Ìpìlẹ̀ ni wọ́n máa kó sórí ẹ, orúkọ ètò ìpìlẹ̀ yẹn ni
BIOS ( Basic Input Output system ) ìtúmọ ẹ ni ètò Ìpìlẹ̀ ti ìwọ́lé àti ti ìjáde. Àwọn ètò ìpìlẹ̀ yẹn ni máa ṣe ìṣakósó gbogbo àwọn ẹ̀rọ agbègbè ayára bíi àṣá nígbà ti ó bá bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́. Ẹ̀rọ ètò ìpìlẹ̀ BIOS yìí ni kọ́kọ́ máa bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ ti ẹ bá tan kọ̀ńpútà yín, lẹ́yin ẹ ni àwọn ẹ̀rọ ìṣiṣẹ́ DOS àti WINDOWS máa wọṣẹ́.

**3.6 Àwọn wáyà ìtanná ( Bus )**

Àwọn wáyà ìtánna ni a máa lò fi so àwọn ẹ̀yà ayára bíi àṣá ( procesor, ẹ̀rọ ìránti ROM, ẹ̀rọ ìránti RAM...) pọ̀. A máa kó gbogbo àwọn ẹ̀yà wọ̀nyìí ti a so pọ̀ sórí káàdì ti apè ni ìyá káàdì.


Wáyà ìtanná oríṣi mẹ́tà ló wà :

- Wáyà ìtanná data ( Inú wáyà yìí ni a máa kó àwọn ọ̀rọ̀, iró gbà )
- Wáyà ìtanná òpoponà ( Inú wáyà yìí ni a máa gbé adírẹ́sì ẹ̀yà ti a fẹ́ lò
- Wáyà ìtanná ìpàṣẹ ( Inú wáyà yìí ni a máa gbé àṣẹ ìfiṣiṣẹ́ àwọn ẹ̀yà kọ̀ńpútà gbà )




**3.7 àwo líle**






Àwo líle jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà agbédéméjì ìṣe, ẹ̀rọ ìrantí ti agbára ẹ pọ̀ gan an ni àwo líle, inú ni a má kó àwọn iṣẹ́ ti a bá ṣe pamọ́ sí, àwo líle yìí jẹ́ gẹ́gẹ́ bíi àpótí níbà ti ẹ bá pari iṣẹ́ yín tán, inú ẹ ni ẹ yóò kó àwọn iṣẹ́ yín pamọ́ sí.

Agbára àwo líle ti wọ́n ń tà lónìí ni Go 500 . Bí tí agbára yẹn ṣe ga, bẹ́ẹ̀ ni ó ti lè gbà ọ̀pọ̀ iṣẹ́ ti ẹ bá parí.

Ẹ má gbàgbé láti máa kó iṣẹ́ ti ẹ bá ń ṣe lọ́wọ́ pamọ́ sí orí àwo líle yìí, bí kò bá jẹ́ bẹ́ẹ̀ ti kọ̀ńpútà yín bá kọṣẹ́, tàbí ti ẹ bá pa kọ̀ńpútà yin láì ko iṣẹ́ yin pamọ́, ẹ yóò padanu gbogbo iṣẹ́ yìí ni.

**III  àwọn ẹ̀rọ agbègbè mín ìn**

**1) Kọ́kọ́rọ́ USB**




Kọ́kọ́rọ́ USB jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀rọ ìrantí alágbára, bíì ẹ̀rọ àwo lílе, ti ẹ bá ṣiṣẹ́ párí pẹ̀lú kọ́ńpútà yín inú ni ẹ yóò kó àwọn iṣẹ́ ti ẹ bá parí sí.
Agbára àwọn kọ́kọ́rọ́ tí wọ́n ń tà lónìí ni ( Go 4, Go 8, Go 16, Go 32 ... ).
Kọ́kọ́rọ́ USB dàbí ẹ̀rọ ìránti alàgbára àlágbéka, a lè lò níbi gbogbo.

**2) CD DVD**




ẹ̀rọ ìranti ni àwọn CD pẹ̀lú DVD náà. Iṣẹ́ ti ẹ bá ṣe lórí kọ́ńpútà yin ẹ lè kó sórí CD àti DVD wọ́nyìí.
Orí CD àti DVD ni a má kó àwọn orin pẹ́lù video sí.
Agbára àwọn CD DVD ti a ń lò lónìí ni Mo 720 àti Go 4 .

**3) Ìbùdo USB**

Ìbùdo USB




USB ( Universal Serial Bus )

Ìbùdo USB ní máa jẹ́ kí a so àwọn ẹ̀rọ mín mọ́ Agbédéméjì ìṣe. Àwọn ìbùdo USB yìí ni wọ́n ń lò gan an lónìí. Lẹ́yin ẹ a tún ni àwọn ìbùdo pọ̀gbà àti ìbùdo jara. ẹ̀rọ ìṣe máa ń lò àwọn ìbùdo fi fi báítì ránṣẹ́ sí àwọn ẹ̀rọ tí ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú.

**4)** Asín



Pẹ̀lú asín ni a máa ṣiṣẹ́ lórí ìbojú ẹ̀rọ ayára bíì àṣá. Àwọn asín yin máa lò ìbùdo USB. Awọn asín mín ìn máa lò ìbùdo pọ̀gbà , tàbí ìbùdo jara. Tí ẹ bá fẹ́ so asín pọ̀ mọ́ agbédéméjì ìṣe, ẹ jẹ́ kó dá yín lójú pé ìbùdo USB kan lé sílẹ̀. Ìbùdo yìí ni asín máa lò fi fi báítì ránṣẹ́ sí ẹ̀rọ ìṣe tàbí fi gbà báítì wá lọ́dọ̀ rẹ̀.

**5) Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà**




Ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ẹ̀rọ ìjáde gẹ́gẹ́ bíì ìbòjú. Iṣẹ́ ti a bá ṣe lórí ẹ̀rọ ayára bíì àṣá, ẹ̀rọ ìtẹ́wé títẹ̀ sítà ni a fi yọ ọ́ jáde. Ọ̀pọlọ̀pọ̀ àwọn ẹkà ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà ló waà , àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọ́n jáde ni ( Sony, Hewlett Parka HP, canon …) .

**6) Olùkà DVD**




Tí a bá fẹ́ kà DVD tàbí CD inú ẹ̀rọ olùkà yìí ni a má fi sí í, ohun náà wà lára àwọn ẹ̀rọ ìwọlé bíi ẹ̀rọ ìtẹ̀wé.

**7) Ìbùdo pọ̀bà ( Parralel port )**




Àwọn ìbùdo yẹn wọ́n kò tún fi bẹ́ẹ̀ lò wọ́n mọ́, àwọn ẹ̀rọ ìtẹ́wé jáde, àwọn ẹ̀rọ skani ti a ń lò nígba kan ni wọ́n máa lò àwọn ìbùdo wọ́ńyìí. Àmọ́ lónìí àwọn ẹ̀rọ yẹn, ìbùdo USB ni wọ́n ń lò.

**8) Tẹléńtẹlé ìbùdo ( Serial port )**




Àwọn ìbùdo tẹléńtẹlé yẹn wọ́n kò tún fi bẹ́ẹ̀ lò wọ́n mọ́ , àmọ́ àwọn ẹ̀rọ mín ìn ṣì tún ń lò wọn. Nítorí nǹkan tí a fi pè wọn ni ìbùdo tẹléńtẹlé , àwọn bíìtì tí ń gba inú wọn má tẹ̀lé ara wọn ni ẹ̀yọ kọ̀ọ̀kan.

**9) Skani**

Àwọn ẹ̀rọ yẹn pé oríṣi àwọn olówó ńlá wà , àwọn olówó Kékeré sì tún wà, àmọ́ ni òdè onìí àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé títẹ̀ sítà máa rọpò skani yìí. Àwọn skani yìí máa yọ àwọn àwòrán jáde.
Àwọn ilé iṣẹ́ ti ń yọ wọn jáde ni ( canon, sony, sharp…).



## IV Àwọn kọ̀ńpútà àti àwọn ẹ̀rọ EITWA

### 1) Ìfihàn


Àwọn ẹ̀rọ ayára bíi àṣá àti àwọn fóònuayára EITWA rọrùn láti lò.
Ti ẹ bá fẹ́ kọ èdè yorùbá bó ṣe tọ àti bo ṣe yẹ, àti èdè àwọn ìlú adúláwọ̀ gbogbo àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé ilé iṣẹ́ EITWA ni kí ẹ lò.
Kí ẹ tó lò àwọn ẹ̀rọ wọ̀nyìí, ẹ ní láti kọ bí tí wọ́n ń ṣe ṣiṣẹ́ gbà.

### 2) **Àwọn ẹ̀rọ ìtẹ̀wé EITWA**




### 3) Àwọn oríṣi bọ́tìnnì

#### 3.1 Bọ́tìnnì oní ìpele méjì




Ìpele àkọ́kọ́ ni "a" kékére a ò kọ ọ́ sí orí bọ́tìnnì yìí nítorí kó má bà gbàyè jù.
Ìpele èkejì ni "A" ńlá, ti a kọ sókè.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "a", a kékeré sí ojú ìbòjú ẹ kàn tẹ̀ bọ́tìnnì yìí ni.
Ti a bá fẹ́ tẹ̀ "A", A ńlá sí ojú ìbòjú ẹ tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì ⇧ "Shift" pápọ̀


### 3.3 Bọ́tìnnì oní ìpele mẹ́ta




Ibi Ìpele àkọ́kọ́ ni ";" agbọ̀nrin.
Ìpele èkejì ni "." ojúami.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀tà ni ">" tóbi jú.

Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ ";" agbọ̀nrin sí ojú ìbojú ẹ yóò kàn tẹ̀ bọ́tìnnì yìí ni.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "." ojúami sí ojú ìbojú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tìnnì "Shift" pápọ̀.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ ">" tóbi jù sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti apá ọ̀tún pápọ̀.

### 3.4 Bọ̀tìnnì oní ìpele mẹ́rin





Ibi Ìpele àkọ́kọ́ ni "ẹ" kékeré wọ́n kò kọ ẹ sí orí bọ́tínì yìí nítorí ko má bá gbàyè jù.
Ìpele èkejì ni "Ẹ" ńlá.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀tà ni "q" kékeré.
Ìpele ẹkẹ́rin ni "Q" ńlá.

Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "ẹ" ẹ kékeré sí ojú ìbòjú ẹ yóò kàn tẹ̀ bọ́tínì yìí ni.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "Ẹ" Ẹ ńlá sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnnì "Shift" pápọ̀.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "q" q kékeré sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì "Alt" ti apá ọ̀tun pàpọ̀.
Ti ẹ bá fẹ́ tẹ̀ "Q" Q ńlá sí ojú ìbòjú ẹ yóò tẹ̀ bọ́tínì yìí àti bọ́tínì "Alt" ti apá ọ̀tun àti bọ́tìnnì "Shift" mẹ́tẹ̀tà pàpọ̀.

### 3.3 Bọ́tìnnì àmì

Pẹ́lù bọ́tìnnì yìí ìyàtọ̀ diẹ́ wà, a má lò bọ́tìnnì yìí fi fi àmì sí orí àwọn iró , kí ẹ tó lò bọ́tìnnì yìí ẹ yóò tí tẹ̀ bọ́tìnnì iró ti ẹ fẹ́ kọ, lẹ́yin ẹ ni ẹ wá fi àmì sí orí ẹ.




Ibi Ìpele àkọ́kọ́ ni "´" ohún kúkúrú.
Ìpele èkejì ni “`” ohún pàtàkì.
Ìpele ẹkẹ́ẹ̀ta ni “ˇ” ohún àkíyèsì.
Ìpele ẹkẹ́rin ni “˜” ohún ìtọ́sí.

Ti ẹ bá fẹ́ fi àmì “´” ohún kúkúrú sí orí “o” bi àpẹrẹ, ẹ yóò ti tẹ̀ “o” yẹn sí ojú ìbòjú, ẹ yóò kàn wá tẹ̀ bọ́tìnnì yìí nígbà yẹn sorí “o” ti ẹ ti kọ, yóò wa di “ó”.
Ti ẹ bá fẹ́ fi àmì “`” ohún pàtàkì sí orí “o” ti ẹ ti tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi apẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tínì “Shift” pápọ̀ ni ìgbà yẹn ni ẹ wà kọ “ò”.
Ti ẹ bá fẹ́ fi àmì “ˇ” ohún àkíyèsì sí orí “o” ti ẹ tí tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi àpẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì “Alt” ti apá ọ̀tún pápọ̀ nígbà yẹn ni ẹ yóò wa kọ “ǒ”.
Ti ẹ bá fẹ́ fi àmì “˜” ohún ìtọ́sí sí orí “o” ti ẹ ti tẹ̀ sí ojú ìbòjú bi àpẹrẹ, ẹ yóò tẹ̀ bọ́tìnnì yìí àti bọ́tìnnì “Alt” ti apá ọ̀tún àti bọ́tìnnì “Shift” mẹ́tẹ̀tà pàpọ̀. nígbà yẹn ni ẹ yóò wa kọ “õ”.